# ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VLO XIV NO 897 LAGOS SATURDAY NOV, 30 — DECEMBER 6 1963 KỌBỌ MEJI (2D)


## Pansaga Jere:

# Okunrin Kan Ni Nwon Ge On Loko Danu Ninu Ile Ale

KADUNA — Gbogbo awọn ero-iworan ti nwọn 'wa si Kotu awọn ọlọpa ni uwọn yanu nigbati ọkunrin ti o ti nñ igba kan ṣe iṣẹ ọlọpa ri, ti oruko rẹ njẹ Cornelius Agbayi bẹrẹsi sọ fun adajọ kotu awọn ọlọpa na nkan ti oju on ri lọjọ ti o'ọ obinrin kan se on mọle, ti o ni lon wa yan iyawo on lale ni, ti o si GE ON LOKO SILẸ; Agbayi ni lati ọjọ na ni on ko ti le ba obinrin lo mọ.

Lọjọ ti awọn ọlọpa mba awọn arufin mẹta kan, awọn Smart Ogori, ẹniti nwọn pẹ ni ọkọ iyawo ti nwọn wipe ọkunrin na wọle to lọ, Ochenata Eze ati Michael Uche ro ẹjọ wipe nwọn pa Agbayi lara, Agbayi paapa ni nwọn kọ gbe sinu apoti 'wipe ki o sọ nkan ti oju rẹ ri fun adajọ.

Agbayi ni nitotọ ni on lọ si ile Ogori lọjọ ti nwọn ge on loko, o ni on ko lọ sibẹ lati yan iyawo rẹ lale ṣugbọn lati gba pọnun marun ti Ogori ya lọwọ on ni.

O ni ko pẹ ti on de ibẹ ni Ogori wọle, ti o ni nṣe ni on wa yan iyawo rẹ ti o ntọmọ lọwọ lale. Wara-'vere Ogori pẹlu awọn ara ile wọn ti fi nkan bo on loju, ni nwọn ba fi ada ge on lori oko kalẹ.

Adajọ ti nwọn nro ẹjọ niwaju rẹ, Mallam Bako, ni on on fẹ ri agẹku oko na, nwọn mu ọkunrin na lọ sinu iyara adajọ nibẹ ni o gbe ti tu ṣokoto rẹ, ti o si fi agekn oko na han adajọ.

Iyawo Ogori ti awọn ọlọpa mba rojọ ni o ti pẹ ti ọkunrin na ti nyọ on lẹnu wipe ki on gba ale fun on, ṣugbọn lọjọ ti o wọle wa ba on ni ọkọ on ba a; iyawo na ni nwọn lu u pi ilukulu ṣugbọn nwọn ko ge loko rara.

Adajọ ni ko tilẹ dupẹ ti nwọn ko bẹ lori danu; adajọ na tun ṣe alayewipe fun nini ti nwọn na ni on ba wọn wi si, nitori na ki ẹnikọkan wọn fi pọnun marun ati ṣile marun tanran si kotu.

---

## Eleha Kan Bori Lo Si Kotu Akoko

IBADAN—Ina mu oniyigi jade ọsan ni ariwo ti gbogbo awọn obinrin ati ọkunrin ti nwọn wa si Kotu-akọkọ ni Oke-Arẹ npa ni jẹta nigbati nwọn ri obinrin ẹlẹha kan ti orukọ rẹ njẹ Saratu Awẹni ti o bori bosẹ bi egungun, ti o bọ siwaju adajọ, Oloye Y B Ogundipẹ wipe on fẹ kọ ọkọ on silẹ.

Adajọ na ni ṣe ko si kan. ẹlẹha na ni ko si nkan o ni iwa ọkọ on na ti orukọ rẹ njẹ Lamidi Akanmu su on patapata. O ni nitotọ on ni o ha ni ẹha, owo idana ti o san lori on koju ogoji ọkẹ — pọnun mẹwa (£10) lọ on si ti mura wa nile lati san owo na pada fun un.

Adajọ tun bi obinrin ẹlẹha na lere ṣe ko ni ja ẹha rẹ, o ni bi Allah ko ba fẹ ki on ja a, on a tete ri ọkọ miran ti yio ha on.

Lẹhin gbogbo alaye yi ni adajọ ba gba fun un wipe ki o lọ ọkọ rẹ ta.

---

## Awon Bo Loju Egungun:

# Riba £25,000 Ha Awon Kan Lorun Ninu Egbe Oselu

EKO— Awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ ti nwọn wa ninu awọn ẹgbẹ oṣelu Alakukọ (NCNC) ti nwọn pe orukọ ọmọ-ogun ti awọn fẹ ba awọn agbalagba inu-ẹgbẹ na ti awọn fẹ ba nkan jẹ fun awọn, ja bọ awọn loju egungun loru ana ninu ipade gbogbo gboo kan ti nwọn ṣe ninu ile gbọgan iranti Ologbe Randle ni Onikan l'Eko; nwọn ni ọkẹ kan o le ẹgbẹdọgbọn pọun (£25,000) owo-obi ti awọn oṣelu awọn ni ki awọn Oyinbo ajoji kan ti nwọn fẹ da iṣẹ tuntun silẹ mu wa ni o le awọn Oyinbo na lọ patapata.

Ọgbẹni kan, D.C Ugwu, akọwe-agba ninu ile iṣẹ Minisita alamojuto eto ẹkọ ti o jẹ ogunagbongbo ninu awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ na ni o kọ ta pẹrẹpẹrẹ silẹ nipa awọn oṣelu ti nwọn sọ wipe nwọn njẹ ijẹkujẹ kiri na.

Ọgbẹni Ugwu sọ fun gbogbo enia ti o pejọ sibi pade na bi awọn Oyinbo ajoji kan ṣe mura lati wa da iṣẹ nla kan-sile—ẹgbẹrin ọkẹ pọnun (£8million) ni nwọn ṣiro gbogbo owo ti awọn Oyinbo na fẹ na lori iṣẹ na si, o si ju ẹdẹgbarin (7,000) awọn ọmọwa lọkunrin ati lobinrin ti uwọn fẹ gba sibi iṣẹ na lọ.

(wo yoku loju ewe kẹjọ)

---

## Iyawo Kan Da'na Sun Ara Re Nitori Oko

MADRAS (INDIA)- Ọpọ lọ ni ọrọ ọkọ jntojanto ! Gbogbo awọn ọrẹ ati ẹbi obinrin arẹwa kan ti orukọ rẹ njẹ Rajeswari Sivasamu ni o ya lẹnu lati gbọ wipe arabinrin na da'na sun ara rẹ nitori ọkọ rẹ ti awọn aworawọ sọ wipe a ku iku ojiji lọdun ni:

(wo iyoku ni oju ewe Kefa)


## LAGOS RACE CLUB

**Members who have not yet paid their Annual Subscription for the year 1963 are reminded to do so before the 31st December.**

HON. SECRETARY.

## Badiru 'Baba Alajo' Oke Arin Jalaisi

EKO-Anu se wa lati gbọ iku Ọgbẹni Badiru ·unmọnu Anjọrin, ẹniti gbogbo awọn ara Oke Arin l'Eko mọ adapọ orukọ rẹ ni BABA ALAJỌ ti o jalaisi ni alẹ ọjọ'ru tise ọjọ kẹtadinlogun osu yi ninu ile ti o ngbe ni 4 Daddy Alaja Street. Ẹni ọdun marundinlọgorin ni

Ologbe Anjọrin jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Ijaiye ti nwọn wa si ilẹ yi lati Abẹokuta ni iwọn nkan bi ọdun marun-dinladọta sẹhin, ni igba Ogun Adubi: iṣẹ a ntun kẹkẹ basikulu (Cycle reparer) ṣe ni o si nṣe nigbana ni 'opopo Daddy Alaja mọ Bishop Street.

Nigbati a wi yi, mọtọayọkẹlẹ ko pọ tobẹ l'Eko iṣẹ a ntun kẹkẹ basikulu si niyi pupọ larin awọn gbajumọ Imale l'Eko, Abẹokuta ati Ibadan.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Ijaiye ẹkat'Eko ṣe ngbẹ nibi isinikuọku ologbe na lana, gbogbo ṣsẹ awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn mbẹ ni Ebute Metta, Yaba, Suru-Lere, Agege Mushin ati Abẹokuta ni nwọn pesẹ sibẹ sibasiba.

Ninu awọn ọmọ mẹsan ti o fi silẹ ni Sikiru, Riyantu Ayinkẹ, Basiru Akanbi, Biliaminu Akanbi Muniru Ishọla, Shẹkinọtu, Shakiru Arẹmu, Sulemọnu Ajao ati Bilikisu Badiru.

A ki awọn omolọku na pẹlu iya wọn ati awọn omo ẹgbẹ Ijaiye nwọn ku afẹku "BABA ALAJỌ".

## Lori Egbe Yoruba Parapo:

# Benson ati Fani-Kayode So Ti Won

EKO — Lori ọrọ ẹgbẹ awọn ọmọ Yoruba ti awọn ni awọn fẹ dẹgbẹ pọ ki awọn jọ ma jirero bi nkan ibilẹ Yoruba yio ṣe ma lọ siwaju, ti awọn enia kan mbu ẹnu - atẹ lu idapọ ti nwọn fẹ dapọ na, ni a gbọ wipe Minisita alamojuto ikede Ijọba, Ọgbẹni T.O.S. Benson ati Rẹmi Fani - Kayọde, igbakeji Olotu Ipinlẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-orun ni awawi awọn alatako ẹgbẹ ko mu rọ rara.

na

Ninn ọsẹ yi ni awọn oniwe irohin kan ni Yaba jade pelu irohin iyanu kan wipe ile Olori awọn adajọ agba, Ọlọla Adetokunbọ Ademọla ni Ikoyi ni awọn ọmọ ẹgbẹ Yoruba Parapọ ati awọn ọmọ ẹgbẹ Odudwa gbe fi ipade si lati ṣe eto bi nwọn yio tiṣe dori kodo ro parapọ da ẹgbẹ oṣelu kan silẹ ti gbogbo awọn ọmọ Yoruba yio pe sibẹ.

Wara were ti nwọn sọ itan arosọ yi jade ni adajọ Ademọla ti ko ọrọ na si wọn lẹnu. O ni kiṣe ọrọ lati da ẹgbẹ oṣelu kan silẹ ni awọn fẹ sọ ninu ile ti on ngbe bikoṣe lati pari ija nla ti o wa larin awọn ọmọ ẹgbẹ Yoruka.

Awọn Ọgbẹni Benson ati Fani-Kayọde ni ko ye awọn si nkan ti o fa ti awọn kan mbinu si ẹgbẹ ibibẹ awọn ọmọ Yoruba nigbati o jẹ wipe olukuluku ibilẹ ni nwọn ko awọn ọmọ ibilẹ ti wọn jọ, ti nwọn si ntun nkan ibilẹ wọn ṣe nibẹ.

Nwọn ni o yẹ ki awọn alatako ẹgbẹ ibilẹ Yoruba yi mọ wipe nibikibi ti Adajọ Ademọla ba gbe wa, iṣẹ ribiribi ni o fẹ ṣe fun ilọsiwaju ẹgbẹ na.

Nwọn ni ki olukuluku awọn alatako na lọ fi ti wọn ṣe ti wọn, ki nwọn ye bu ẹnu ẹtẹ lu awọn ọmọ ẹgbẹ Yoruba.


**MERCEDES — BENZ**

*Vehicles are Built to last, to give many years, and many miles of trouble-free, economical Service.*

MERCEDES-BENZ



**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, APAPA, IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA.

*Sub-Distributors:—*

**ARMELS TRANSPORT LTD.**

BENIN-CITY . ONITSHA . ABA.


# Oba Benin Nlo Si Ilu Ibo

BENIN CITY — Irohin kan ti a gbọ ni irọlẹ ana ni ti Ọba Benin, Alaiyeluwa Ọba Akenzua keji ti o fẹ lọ ba awọn ẹlẹsin Imale ilu Ibo si ile ijosin orisa wọn ti nwọn fi owo ribiribi kọ si ilu Pọta (Port Harcourt) ninu osu ti a bọ si yi.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ lati ọdọ awọn aluja Ijọ Imale (Godion Religion) na, Oba Binin yio fi ilu Benni sile ni owuro kutukutu ọjọ keje osu kejila odun yi wa si Pọta ọna Onitsha mọ Owerri Umuahia ati Aba ni yio gba. Lọjọkanna ni yio de ilu Pọta (Port—Harcourt) na.

A gbọ wipe Oba Benini yi ko ti ese re kan ilu kan ni Ipinlẹ Ila Orun ri lọjọ ti o ti gun ori itẹ lati nkan bi ọdun ọgbọn ọdun sẹhin. Lẹhinti Ọba yi ba ba wọn si ile ijọsin wọn na tan a rin ilu na kakiri lati wo gbogbo awọn ile iṣẹ orisirisi ti nwọn ṣeṣẹ da sile bi ibiti nwọn gbe ti nmọ awo tanganran ati ile ọti bia.

Olofintoto Ni:

# Nkan Kaan Ni Ose To'koja Yi

## Kennedy Oninure

Awọn agbalagba kakiri gbogbo agbaiye ri nkan to ki nwọn to sọ wipe ko si ẹnikan ti o le tẹ aiye lọrun. Ẹnyin ara mi, nkan kaan ninu ọsẹ ti o kọja yi nipa pipa ti nwọn yinbọn pa balẹ awọn ara ilu Amẹrika, Ọgbẹni John Kennedy, ni ọjọ Eti (ọjọ Jimọ) ti o kọja ni ijẹsan, nigbati o nlọ ba awọn ara ilu Dallas şi ipade ajọdun awọn onşowo ilu na.

Eni ọdun mẹtalelogoji ni balẹ Kennedy, wa ti o ti şu ọşuka, ti o si gbe wahala alakoso Ijọba Ilu Amẹrika lori. Ki ẹnyin ọkawe mi ma şi mi gbọ lati şe alakoso Ijọba ilu Amẹrika kişe nkan ti o rọrun rara, nitoripe bi o ti nşe wahala rogbodiyan ti awọn ara ilu rẹ nile, ni wa tun ma gbe wahala Ijọba okere şokan.

### Ore Alawodudu

Ilu Amẹrika jẹ ọkan ninu awọn alagbara aiye, nwọn ni owo lọwọ, nwọn ni onjẹ loko, nwọn si ni nkan ija lapo. Ko si ẹgbẹ wọn alagbara ti o le ko iyan wọn kere.

Ilu Amẹrika jẹ ilu kan ti awọn alagbara aiye ma nwo ki nwọn to lo firu fọnna nibi kan. Nitori eyi gbogbo awọn ara aiye ni nwọn ma nşọ ẹrọ ẹnu balẹ ilu Amẹrika ati iwa rẹ. Bi awọn ara ilu Amẹrika ti lowo lọwọ si, ti nkan ọwọ wọn to wọn jẹ, airoju, airaye wa larin awọn ara ilu na ti nwọn jẹ alawọfunfun ati awọn alawọdudu ti nwọn ti mba wọn gbe lati ọdun mọdun.

### Eni Aiye Nfe

Ko digba ti o ba jẹ olowo tabi lọya ki awọn ara ilu Amẹrika to dibo lati yan ọ gẹgẹbi oşelu ti ile Igbimọ aşofin rara. Ko digba ti o ba mọ ọna-eru ati ọgbọn-ẹwẹ lati rẹẹ awọn arailu rẹ jẹ, kiỌọma fi işẹ oşelu kowo j , ki nwọn to yan ẹ ni alakoso Ijọba Ilu na. N an t o ni lati ni ni ako kanju ati suru lati ba onişoşi enia lo.

Ologbe Kennedy jẹ ọdọde ti o fi suru ati iwa akinkanju rẹ mu opo aiye duro doni lọdọ awọn alagbara aiye, ti ko jẹki a ti ri ogun ati inajẹ si e. wọn Ọlọgbọn aiye ati awọn alagbara si ka a si ẹ iti ọpọlọ rẹ pe papọ nipa nkan işelu.

### Kennedy Pegede

Nigbati ede aiyede bẹ silẹ larin awọn ara ilu rẹ alawọfunfun ati awọn alawọdudu ti awọn Oyinbo ilu meaika ni awọn ko fẹ foju kan wọn nibiti awọn ba gbe wa, Ologbe Kennedy ni ọrọ kişe ọrọ ija o ni ọrọ ori ko ju ori lọ ni, o ni bi a ti bi ẹru ni a bi ọmọ; balẹ Kennedy ni ẹnikan ko ja wa lati oju ọrun. O bọ şokoto rẹ o si mura si ọrọ na.

Eleyi ni irohin ti o jade nipa nkan tibiribi ti Ologbe Kennedy şe lori rogbodiyan awọn Oyinbo alawọfunfun pẹlu awọn enia dudu ilu Amẹrika na.

### Kennedy Bale Ilu Amerika Pegede

Ka ko ti ẹgan koro ninu ọrọ ti o wa nilẹ, balẹ Kennedy işe alakoso gbogbo ilu Amẹrika se ede ori ọrọ awọn ọmọ alawọdudu akẹkọ meji ti Gomina ilu Alabama, Ọgbẹni George W ce s gbogbo agbara rẹ wipe awọn ko gba awọn ọmọ akẹkọ n sinu ilewe giga ti awọn alawọfunfun ti awọn ọmọ na fẹ lọ ma kọ ẹkọ.

Tẹlẹtẹlẹ nigbati Gomina ilu Alabama ti ngbọ irohin wipe awọn ọmọ akẹkọ alawọdudu fẹ fi oruko silẹ ati wọ ilewe giga na ni Gomina na ti nleri kakiri wipe ko nşe ni aiye ti on ni awọn alawọdudu yio wọ ilewe na.

Eyi mu ki awọn alakoso ofin ilu Amẹrika gbe ọrọ na lọ si Kotu, adajọ Kotu ti nwọn gbe ọrọ na lọ si paa laşẹ wipe Gomina na ko gbọdọ di awọn ọmọ alawọdudu kan lọwọ rara lati forukọ silẹ lati wọ ilewe giga ilu na.

(Wo yok loju ewe kẹfa)



DA EHIN-DIDUN RE DURO

nipa titete mojuto awọn eree inu ati apo-itọ rẹ

LO

DeWitt's Kidney & Bladder Pills

M e si bọ lọwọ awọn irora ti o nkọ ẹ sinu arun

LAKUREGBE, ARA-RIRO, EHIN-DIDUN ati, Awọn IYỌNU APO-ITỌ

DeWitt's Kidney & Bladder Pills


ENIA MẸTA KU PẸLU KENNEDY:

## Okunrin T'opa Kennedy Pade Agbako

DALLAS (USA) Lee Harvey Oswald, ẹni ọdun mẹrinlelogun ti awọn Ọlọpa ilu Amẹrika si gbamu wipe on ni o pa balẹ ilu wọn, Ọgbẹni John Kennedy, ti nwọn yinbọn fun ninu mọto yẹ si ilu Dallas ni owuro işun n b wọn pari Oyinbo Amẹrika kan, J c yinbọn mọ a on ọlọpa lọwọ.

A gbọ wi e lati ọ ọ ti awọn ọlọpa ilu Amẹrika ti mu Osw ald lati ọjọ Jimọ ti o kọja, ni ẹsan ọdọ wọ ti o gbe wa ti nşe iwadi ọrọ re pẹ ti o ko fi ra ibọn ti o lọ na lọdọ awọn ti nwọn nta ibọn.

Akọwe onirohin wa ni bi awọn Ọlọpa ti wọ ọkunrin arufin na jade ni ile lati gbe wọ mọto gba ẹgba awọn lọ ki to mọ eyiti awọn yio şe ripa

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

### Isinku Kennedy Lana

WASHINGTON D.C.— N nwọn ti nsin oku awọn Ọlọla tabi awọn J gu lagan, ko gbọ iru ẹ ti nwọn şe eyi ati iyi to fun bi nwọn şe fun Ologbe John John Kennedy ti e balẹ ala-

(Wo yokuloju ewe kẹfa

# ELETI-OFE

(ANJU WỌN KOSE WI LẸJỌ )

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMS
28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23970

VOL XIV. NO 897 SATURDAY NOV. 30 - Dec 6, 1963


## Oro Olotu:

# Kennedy: Ti Won Loju

Awọn Yoruba ni nwọn pa owe nla kan: TẸNI BẸGI LOJU, TI O B\ PẸ IGI A TUN PADA RU EWE. Ẹ jọwọ ẹnyin ọkawe wa ẹ fi ori jin wa, owe na owe awọn agba ni, awọn awaiye-maṣere kan ti nwọn pa Ologbe Ọgbẹni John F. Kennedy, balẹ ilu Amẹrika, olore gbogbo agbaiye ni a si nfi owe tamutamu yi bawi.

### O Se F'Alejo

Ninu gbogbo awọn oṣelu ti nwọn wa kakiri lode aiye ti oni, ti nwọn nfẹ alafia fun gbogbo aiye, ti nwọn ko fẹ inira fun ẹnikan, o ṣe alawọfunfun ni tabi alawọ-dudu ni, Ologbe Kennedy ni o bori gbogbo wọn.

Boya ọpọlọpọ ẹnyin ọkawe wa le bere wipe kinni nkan rere ti ologbe Kennedy yi ṣe fun wa ni Nigeria ti o fi di wipe a mba wọn kẹdun Ọgbẹni Kennedy na to bayi. Ṣe berebere kiṣi bere. Awa Onirohin Eleti-Ọfẹ mọ wipe ỌRẸ WA ATATA NI ILẸ AFIRIKA NI OLOGBE KENNEDY. La i ọjọ ti o ti gun ori aga iṣẹ alakoso Ijọba ilu rẹ ni o ti bẹrẹsi gbe wahala wa sọkan bi yio ṣe tu ti yio ba a fun wa.

### O Se F'Onile

Awọn sọrọsọrọ ti nwọn mọ nkan nipa iṣẹ ribiribi ti awọn oṣelu pataki pataki nṣe lẹhin balẹ kan ti o ti jẹ ni ilu Amẹrika na ti nwọn npe orukọrẹ ni Abraham Lincoln, ni ko si ẹni ti o ṣeiṣẹ pataki fun gbogbo agbaiye to ologbe Kennedy ti awọn ẹlẹmi ẹṣu pa yi.

Ki a wa pada wa sile; melo ni ki a ro nipa iranlọwọ ribiribi ti o ṣe fun awa ara Nigeria. Akoko Ọgbẹni Kennedy ni nwọn da ẸGBẸ IRANLỌWỌ ALAFIA (Peace Corps) silẹ fun iranlọwọ gbogbo abgaiye nilu ti agbara wọn ko ti to nkan ṣe fun ara wọn.

O to ẹẹgbẹta (500) awọn olukọ ọmọ ilu Amẹrika ti nwọn ran si wa ni ilẹ yi wipe ki nwọn ko ma kọ awọn ọ ọ wa ni oriṣiriṣi ẹkọ ni ilewe ati ninu oko iọlẹ, ki a mọ ṣẹṣẹ tun sọ nkan owo tabua, bi ẹru iroko, mọto ti o nla ọna ati awọn nkan bẹẹbẹ ti Ijọba ilu Amẹrika fi nta gbogbo agbaiye lọrẹ.

Bi awọn ara ilu Rọṣia (Russia) ti nleri wipe awọn ti to tan, awọn Amẹrika tun nfi nkan onjẹ ṣe iranlọwọ fun wọn, Ologbe Kennedy ti sọ nigba aiye rẹ wipe on ko fẹ ki iya jẹ ọmọ araiye kan.

Ki a to pari ọrọ olotu wa ti ọsẹ yi, a fi tọkan tọkan gbadura fun balẹ tuntun ilu Amẹrika Ọgbẹni Lyndon B. Johnson, igbakeji ologbe Kennedy, ti nwọn gbe ọpa iṣoro alakoso ilu Amẹrika le lọwọ lati ijesan ,wipẹ ki Oluwa Olodumare ki o ba gbe ẹru na dori.

Ti ologbe Kennedy ti di tẹni bẹgi loju igi a tun pada ru ewe.

# Iwe Si Olotu

## Nitoto Nwon Nfe Iranlowo

Mo gbadun ọrọ otitọ ti Olọtu sọ ninu iwe Eleti-Ọfẹ ti/ November nipa awọn Oniṣegun ibilẹ ilẹ wa ti nwọn gbarijọ lati gbe ogo ilu wa dide nipa ile iwosan tuntun ti nwọn ṣi si Ita Faji l'Eko lati maṣe iwosan fun gbogbo awọn enia wa.

Olotu, mo gba fun ọrọ yin ti ẹ sọ wipe o yẹ ki awọn alamojuto eto Ijọba wa ṣe iranlọwọ fun awọn ẹgbẹ oniṣegun ibile na ki nwọn le tẹ si iwaju si. Awọn Yoruba ni yinni yinni ki a le ribi ṣeomiran.

O da emi loju wipe bi Ijọba wa ba le ṣe iranlọwọ fun awọn ẹgbẹ yi tabi iru awọn ẹgbẹ miran ti nwọn nṣe iwadi bi a ṣe le lo awọn egbogi ilu wa si ọna rere, a dara pupọ.

Nigba gbogbo ni awọn minisita ilu wa nnawo gọbọyi lọna ti ko le mu anfani wa fun awọn ara ilu. Owo ti a ba na lati ṣe iwadi egbogi ibilẹ wa kiṣe ọna buruku rara, iyi ati ẹyẹ ni yio jẹ fun awọn ọmọ wa lẹhin ọla.

Iru iṣẹ iwadi nkan rere bayi ni awọn Oyinbo ma nnawo si. Mo si kan saara si awọn ọmọ ẹgbẹ oniṣegun na, ki nwọn ma tẹ siwaju si, Ọlọrun yio ran wọn lọwọ.

Agbokojo, Ibadan

Emi ni,
S. Ọyalọla

## Ile Iwosan Ibile

Olotu ẹ kọ iwe kan laipẹ yi nipa ile iwosan ibilẹ ti awọn ẹgbẹ oniṣegun ti orukọ wọn njẹ Nigeria Association of Medical Herbalist ṣẹṣẹ da silẹ ni igboro Eko, ti ẹ tun sọ wipe nwọn ni ẹka kakiri.

Mo gba fun ọrọ iṣiri ti ẹ sọ fun wa wipe ki a gbaruku ti wọn O dabi ẹni wipe mo ti ngbọ orukọ awọn ẹgbẹ oniṣegun ibilẹ bayi ti pẹ ṣugbọn nko mọ wipe awọn na ti nṣe iṣẹ ribiribi bayi.

Boya bi ẹnyin oniwe irohin ti kesi awọn enia wa Ọlọrun a a jẹki nwọn gbọ, ki nwọn si gba. Ṣe ẹnyin na mọ wipe nkan awa enia-dudu ko ntete jọwa loju. Adura mi si ni wipe Ọlọrun ma jẹki o tete rẹ awọn alakinkanju ti o da eto iṣẹ ile iṣegun ibilẹ na sile, ki nwọn si legbe e dori.

Imọ, Abẹokuta

Emi ni,
E.A. Akinsọla

# O Da Won Loju!

Olotu, ẹ jọwọ ẹ ki ọrọ awọn oniṣegun ilẹ wa ti ẹ sọ wipe nwọn ṣẹṣẹ sile iwosan si ita Faji l'Eko ti ẹ sọ wipe nwọn wo arun ara ọkunrin ati obinrin san bi 'dan, nitoripe awọn Oniwayo oniṣegun pọ laiye nisisiyi.

Mo ti nka iwe Eleti-Ọfẹ ti pẹ, mo si gba gbogbo nkan ti mo ba kaninu iwe na gbọ nitoripe ẹ ki parọ ninu iwe irohin yin nkan ti o ba ta si nyin leti ni ẹ ma nsọ jade. Ẹ jọwọ ẹ la iṣẹ awọn Oniṣegun na ye mi.

Porto Novo, Dahomey

Emi ni,
M. Dauda

ALAYE SOKI NI AO ṢE FUN Ọrẹ wa Mustafa Dauda, ti o fẹ ọmọ bi Olotu ni awọn ti o da iṣẹ iṣegun awọn Nigeria Association of Medical Herbalists silẹ ni nomba mẹta (3) ni Opopo Willoughby nita Faji l'Eko.

Nwọn bi ogun eni ba dani loju ori ni a fi nkan. Ni ijẹta ti OLOFINTOTO wa lọ tun bẹ ilewosan na wo, ogunlọgọ awọn enia ni o ba nibẹ lọkunrin ati lobinrin ti nwọn wa fun iwosan ọfẹ.

Lẹhin Dokita Z O. Salimon, awọn mẹta ti o tun ri ni Ọgbẹni L. A. Adẹṣegun, Afọlabi Dawodu ati Musa Ọba Anigilaje ti nwọn nsare sihin sọhun lati le te gbogbo awọn enia ti wo ara wọn san lọrun. Mo gbọ wipe lẹkọkan loṣu ni nwọn nṣe bayi lati fi han wipe egbogi wọn da wọn loju.

— OLOTU

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

## Kennedy Woli

Bi emi Ayiluka ti ndagba si lodọdun ni mo nri wipe ọrọ kan ti mo ti ka ninu iwe BIBELI wipe, O TỌ AWỌN ENIA TIRẸ WA ṢUGBỌN NWỌN KO SI MỌ Ọ, lojojumọ ni ọrọ na nṣe ni arin wa. Ẹ jọwọ enyin ọkawe mi, ẹ maṣe ba mi pe nigbawo ni emi Ayiluka di Oniwasu ati wipe nibo ni Ṣọṣi mi pẹlu awọn ọmọ Ijọ mi wa. Ọrọ lo ko mi ko mo ro wa.

Iku Ologbe Kennedy, baalẹ alakoso Ijọba ilu Amẹrika ti awọn ara ilu rẹ pa ni ijẹsan dun mi pupọ. Igbesiaiye Jesu Kiristi ni mo fẹ le fi ti Ologbe Kennedy na we. Nigbati Jesu wa ni aiye ti o nṣe iwasu fun awọn ara rẹ wipe ki nwọn ni ifẹ arakunrin wọn gẹgẹbi ti ara wọn, ki nwọn maṣe ba ara wọn jagun, ki nwọn ma gbe igbe alafia; awọn ara ilu rẹ ni ẹnu rẹ nrun, ki o ba tirẹ si iwaju; ṣe on ni o yẹ ki o wa wasu alafia fun awọn? Tani o tilẹ bi i? Sibẹ sibẹ nwọn pa a ni.

### Alafia

Lọjọ ti Ologbe Kennedy ti bọ sori aga Alakoso Ijọba ilu rẹ ni o ti nsọ fun awọn enia rẹ wipe ki nwọn nifẹ awọn alawọdudu ti o wa larin wọn, ati awọn alagbara aiye, ki nwọn ye rọ bọmbu oloro— WOLI ALAFIA ni on. A fi igbati awọn ọmọ araiye fi ọta-ibọn fọ lagbari wipe ki o dakẹ rẹ nbẹ ni nwọn to dẹhin lẹhin rẹ. Ṣe enyin na wa ri wipe nitotọ ni o tọ awọn enia tirẹ wa lati ṣe nkan rere fun wọn ti nwọn ko si mọ?

### Ijo Baptist

Emi Ayiluka ki Dokita E A Dahunsi, Alfa Ijo Ṣọṣi Onitẹbọmi (First Baptist Church) ni Eko ku abọ nitoripe a ejo ni Alufa Ojiṣẹ Ọlọrun na jẹ larin wa l'Eko bi o tilẹ jẹ wipe o ti wọlu Eko tipẹ, mo ṣeṣe ri aye lati ki ku abọ ninu ọsẹ yi gẹgẹbi Ayiluka Eleti-Ọfẹ

### E Ku Alejo

Ona ti mo ni lati fi ki Alufa Dahunsi ku abọ pọ, lọna kini Ijọ Onitẹbọmi ni emi Ayiluka, ṣugbọn mo ti di ọkan ninu awọn aguntan ti o sako lọ; nkan ti o fa eleyi temi pẹlu Ọlọrun mi lo ye.

Lọna keji, eto-isin tuntun ti mo ri lọwọ Eni-Ọwọ Dahunsi na jẹki o ya mi lara lati kan sare si i wipe o ku iṣẹ emi. Bi o ba ti wọ Ṣọṣi nla ti awọn Ijọ Onitẹbọmi (First Baptist Church) l'Eko lọjọ isinmi ni nwọn ma nha iwe eto-isin fun gbogbo nkan ti nwọn yio ṣe ati eyiti nwọn tiṣe lọsẹ ti o kọja fun ọ. Eleyi wu mi o!

## Kini Ola yio Ti Ri?

Mo gbọ wipe Ọgbẹni wa Dokita J A Adegbiẹ, ọga ile ẹkọ giga wa lati Bariga ni o ṣe iwasu owurọ ti ọsẹ ti o kọja, ti Ọgbẹni Akinrẹmi Cole atẹduru Ijọ fi orin dundun bẹẹ. Nitotọ ojọ oni ni ... r, a ko mọ bawo ni ọjọ ola yio ti ri.

Boya ẹ le lọ si Abeokuta tabi Ogbomosho, ki ẹ ba mi ki awọn Alufa AGBOOLA ati baba wa, Alufa J A ADEDIRAN; ẹ si ku ... le Dokita George Green, oninure ti o fi gbogbo igbesi aiye rẹ ṣe iṣẹ iwosan fun wa ni Ogbomosho, ki o to jalọ si ... yi ni Amẹrika. IWA WỌN SI NTỌ WỌN LẸHIN.

**Ra ELETI OFE ni ọse ti mbo, Ayiluka yio so otito fun awon ara Eko.**

# EWu Asiko



**Ewu asiko ti awon omoge ilu Oyinbo fe gbe jade ninu odun Keresimesi ti mbo niyi o yato si 'Mafogota" ti awon kan nwo kakiri ilu ni Nigeria nisisiyi.**

# Nkan Kaan Ni Ose T'okoja Yi

(O bere loju ewe keta)

GOMINA LERI

Awon olopa ilu Amerika fun Gomina nayen iwe ase ti adajo na pa, sugbon o ni tire ni o so yen. O ni ti o ba di ojo na ki awon ara ilu on mu wo nkan ti on u se; nwon ni ti gomina yi ba rufin adajo na nwon a le ju u sewon odun mewa pelu ise asekagun.

Nitoto ni ijeta ti awon omo enia dudu meji na James Hood ati omoge Vivian Malone fe wo ilewe giga na, Gomina yi lo duro s'enu ona o ni "ko sai-ye" Boya o nse eleyi ki awon ara ilu re ba le tun dibo fun un wole ni sugbon nigbati gomina yi ri awon soja omogun ti Baale Kennedy fi ranse si ilewe na pe bi o ba ti gba ni ki won se, gomina na fehin si e o salo patapata.

Bi o ti nsalo ni o bere si fonu wipe "ija na sese bere ni o, o n a ri wipe nwon yo awon omo na ninu ilewe patapata.

Baale Kennedy ni laipe yi on a ri wipe awon iko ile igbimo asofin fowo siwe ofin ti nwon fe gbe jade lati dero inunibini ti awon Oyinbo Amerika nse si awon alawodudu. Baale na ni nigbati nwon gbe wahala egun ti awon enia dudu yi ni awon kesi nwon da awon lohun logan nitori na ese ni bi awon alawo funfun ba wa beresi se ikorira si awon enia-dudu yi.

OFINTUNTUN

Laipe yi ni bale Kennedy tun sese gbe ofin titun jade sile igbimo awon asofin nipa rogbodiyan awon alawofunfun pelu enia dudu ti nwon ko jeki aya ilu bale Awon asofin ilu Amerika ti nfenu pa ofin tuntun na ki wonpari nkan to jade lati paa ni apafon.

MU U DURO

Mo gbo wipe nwon ba iwe pataki kan ti Ologbe Kennedy ti fe ba awon ara ilu Dallas omo uwabi ninu apo re nigbati o ku, okan ninu ese ose na ti o pataki ninu oro ti Kennedy bale ilu Amerika fe so ti nwon mo lenu ni "A FI BI OLUWA OLORUN BA SO ILE NA BI BEKO AWON TI O NSO O LASAN NI"

Se sayin omo Nigeria wa ri wipe aiye ti awa nisisiyi ti ka ese kan nile, okan ti o ku na ko si tobe mo ? Olorun ki o yo wa ki o gba wa lowo awon alagbara aiye pe u irokeke ogun ati bombu Oloro ti nwon ti se jo.

John Kennedy, ONINURE, ENI-AIYE-NFE, ORE ALAWODUDU, Olorun ki o gbe e si afefe rere.

# Enia Meta Miran Ku Pelu Kennedy

NEW YORK— Lehinti ogbeni Jack Ruby ti yinbo pa Lee Oswarld ti o yinbon pa ologbe John Kennedy, alakoso Ijoba ilu Amerika, o di enia meta ti o gbo irohin pe nwon ku ni tele-ntele lori iku Kennedy na.

Okan ti o ya wa lenu ni ti Ogbeni ara ilu Chicago kan ti oruko re nje Theo Mrazchzak, ti o so fun iyawo re lehinti nwon ti gbo ikede iku Kennedy ninu redio tan wipe kinni on tun nse laiye ti ou ko ba bale Kennedy lo. Wara-were o ti ki ibon re mole, o si yin si agbari arare, o si ku bamubamu:

Ekeji ni ara ilu Iowa kan ti o gba baba iyawo re lo'e ni agbedu nigbati iyen beresi bu Kennedy wipe atorun doruu re, aku-tuu-ku re lode won ti nwon joko si, ti nwon nwo oworan isinku bale Kennedy.

Eniketa ni olopa kan ti a tun gbo wipe nwon pa ni gbara ti nwon ti yinbon pa Kennedy nigbati nwon nfe mu eniti nwon fura si wipe on ni o yinbon pa Kennedy na.

Obinrin kan ti oko re ku soguu, ti bale Kennedy si ti nran lowo lati odun gboro, Iya-afin Jack Kirksley ni a gbo wipe awon kan fi oro fonu so fun wipe ti ko ba ye se anu awon enia-dudu, awon yio pa a ni apafon.

# Okunrin T'opa Kennedy Pade Agbako

(O bere loju ewe kefa)

oro re ni okunrin elegiri kan sare yo jade lehin awon oniwe irohin ati awon onifoto iwe irohin ti o si ta odaran na nibon ni agbedu, oku wa di meji ni koto.

Wara-were awon olopa ti sare gbe gbe digba-digba lo lo si ile iwosan ti awon gbo Kennedy ti on pa lo, ko pe ti nwon ru u de ibe ni o jalasi Ni owuro kutu ojo Aje nwon sinku Oswald ni ilu iya re.




## Isinku Kennedy Dun

koso ijoba ilu Amerika ti nwon yinbo pa ni ijesan ti nwon si sinku re ni ijarun ojo aje.

Gbogbo awon Ijoba alagbara agbaiye ni nwon pase sibe ninu Sosi awon Aguda ti nwon npe ni St Matthew Cathedral ni nwon ti se isin igbehin fun un; Padi-agba, ni o se alakoso isin isinku na ki nwon to gbe oku na sin si inu ite ti nwon nsinku awon alakoso si.

# Eleti Ofe Daraba

# Nigeria Wins British University Price

LONDON — A Nigerian medical student in Britain has won a top anatomy prize, beating twenty British fellow-students to gain the award.

He is Mr. Emmanuel Eronini, son of Chief Umez Eronini, of Port Harcourt, who is studying at the Welsh School of Medicine, Cardiff.

Emmanuel Eronini, who is reading anotomy for an honours degree before qualifying a doctor, has won the Alfred Hughes Silver Medal for outstanding work in the Schools anatomy class.

In the competition-open to senior members of a class of anatomy - Mr. Eronini was the only overseas student to compete this year. The medal is in memory of Proffessor in Anatomy in the University College of Wales.

Mr. Eronini went on to study in Cardiff from Woodybury Down Comprehensive School, north London, where he gained his ordinary and advanced level G.C.E. A year ago he was awarded a wellcome Trust Scholaship enabling him to assist two senior lecturers in research work, which was valuable experience," he said.

## Nigerian "Jumps" Cambridge To Victory

LONDON— A Nigerian undergraduate athlete helped Cambridge to score a convincing victory over Oxford in the University Field Events match last week.

A. O. Oyenuga of Ijebu, Western Nigeria, a second year student of archeology and anthropology at Dowing College, won the long jump event with a leap of 21 ft. 11 ins. and came second in the triple jump with 45 ft. 6 ins.

The Cambridge victory by five events to two was their fourth in a row and set both an event and an individual record. In the triple jump the winner, Eric Robinson, topped the the record by 11/2 ins. with 46 ft 5 ins and the aggregate of 180 ft 71/2 ins bettered the old total by 131/2 ins

## More Nigerian Coins Struck By Britain's Royal Mint

London — Britain's Royal Mint struck over 105,000,000 coins ever highest production.

A total production of 774,000,000 coins of which 36 per cent was for countries overseas, included, over 8,000 000 shillings for Nigeria dated 1 61, over 177, 000, 000 shillings dated 1962 and 20,000,000 pennies dated 1959.

These figures are given in the ninety-third Annual Report of the Royal Mint published in London today, covering the year 1962 In addition, a new public seal for Nigeria was designed at the Royal Mint, modelled by Mr. Cecil Thomas.

In all, eighty-seven different currency denominations for twenty-four countries were produced at the Royal Mint in London last year, including francs for the Republic of Guinea.


DAGENITE

BATTERIES

*give you a longer run for your money!*




★ longer life
★ improved electrical efficiency
★ increased shock-resistance
★ fitted with Porvic Separators
★ dry charged


## Nigerian Major To Study British Industry

A senior Nigerian army officer will be one of a party of Commonwealth officers who will next week see something of British industry as part of their course of training at the Staff College, Camberley, southern England

He is Major D. A Ejoor of the Nigerian Army now taking his third course in Britain.

With seven other officers, from Australia, Canada, Pakistan, Malaya, Rhodesia and America, Major Ejoor will next month visit Bristol, Gloucestr and Melksham. After discussions at the Board of Trade Regional Office they will see aircraft and ir engine factories, tout the British Nylon Spinner factory and Fry's ch clat works and see over the Avon Rubber Company production.

The Camberley course while consisting mainly of military studies, also aims to broapen he knowledge of students in a more general field. And as defence policies must be supported by a soun economy it is recognised that the efficiency and prosperity of industry are matters of importance and interest to the Services.

Maj Ejoor was commissioned from the Royal Military Academy, Sandhurst, in 1956 and in 1958 was selected to attend a course at the Royal School of Infantry. He has served in he Congo for a year as Company Commander.

## Awon Egbe Agbe Binu Kuro Ninu Egbe Alakuko

IBADAN Oro behin yo! Gbogbo awon omo egbe agbe ti o mbe ni Ipinle Iwo Orun ti awon ni eka kakiri gbogbo ile bi ona metaleladorin ni awon ko ba awon omo EGBE OSELU ALAKUKO (N.C N.C se ajosepo mo. Nwon se ipinnu yi ninu ipade apapo kan ti nwon se loru ana.

Baba egbe won, oloye R I Ajila ni o beresi se alaye oro na fun onirohin wa kan lana. O ni o to odun meta nisisiyi ti awon omo egbe on ti gba lati ma dibo wole fun enikeni ti awon omo egbe Alakuko ba mu sile.

O ni o ni orisirisi ileri ti awon olori egbe na se fun awon ki awon to gbonge fun won lati ma ba won se po, e ni sibesibe awon olori egbe na ko nani enia rara.

Oloye Ajila ni a tile gbo igbati nwon ko tile nawo gan Ijoba, sugbon nigbati awon ti gun ori alefa Ijoba Ipinle Iwo Orun nko?

Olori awon agbe na ni bi iwaju ko ba se lo, ehin a se pada si. O ni gbogbo nkan na yato si igbati awon mba awon OMO EGBE OLOPE (A G) lo. O ni awon yen mba awon ro ona bi nkan ogbin awon yio se lowo lori dara-dara.

Oloye Ajila ni bi "akoko lati di idibo ba de awon na a ko awon enia awon sita lati dibo fun ara won-ada ti awon fi nroko ni awon yio fi se ami ti won.

---

## Awon Bo Loju Egungun

(O bere loju ewe kinni)

O ni gbara ti awon Oyinbo yi ti so fun awon anikanjopon Oselu ti a ni ki nwon ma ba wa se eto ile wa yi, nse ni nwon ni ki awon Oyinbo na ko ba awon wa owo obi tawon. Nwon ni ko si nkan ti yio gba ti yio din ni oke kan o le egbedogbon ponun) (£25,000) ki owo na to pin larin awon.

Nigbati awon oga ti nwon ran awon Oyinbo na gbo eleyi; iwe waya ni nwon fi yara pe awon Oyinbo na pada silu won. Ogbeni Ugwu ni ko nipe ki ija nla to be sile larin awon mekunnu ara ilu pelu awon oselu wa. O ni awon mo won, awon si fi oruko be won lasi ni si e.

## Iyawo Kan Da'na Sun Ara Re Nitori Oko

(O bere loju ewe kinni

Bayi ni a gbe irohin na si, nwon ni Obinrin na ni kolu-pampa kan (pendant) ti awon obinrin ma nle ma'ya, sugbon ko mo bi nwon se gbe e mo on lowo, o ni boya on ko mo ibiti on gbe ju golu-aya na si ni, idi re niyi ti o fi mu owo to awon aworawo lo wipe ki nwon ba on ye e wo.

Baba aworawo ni ki obinrin na fowo kanle ki o tun fi kan aya re, o ni ti ko ba se e utu nkan ti o ju golu-aya lo ni yio be lowo re ninu odun yi.

Aworawo ni ki n se toto fun un, oko re ti o nsise awonle lodo Ijoba yio ku iku ojiji.

Kinni arabinrin yi gbo eyi si ? Nse ni o pada lo si ile re, ti o lo ra garawa epo Oyinbo (Kerosene) eji ti o po mo epo-moto, ti o da sara, ti o si kan'na si i, obinrin na si ku bamubamu sinu baluwe ti o ti se ara re mo na.

---

## Eja Panla Da Gbese Sile Fun Awon Onisowo Kan

EKO— Adajo Kotu nla kan, Ogbeni Carxton-Martins, da ejo gbese kan ti awon Oyinbo onisowo eja panla kan awon Tracey Blagden, pe awon onisowo ilu Eko kan, awon ti oruko egbe isowo won nje AJAO BROTHERS, wipe ki nwon lo san egbejidinlogoji ponun (£7, 600) fun awon oyinbo oni eja pala na pelu ponun marundinlogofa ati sile mew (£115, 10/- owo-irin ese.

Egbejilelagoji ponun (£8,400) ni gbogbo owo eja panla ti awon Oyinbo na ni awon fi ranse si awon Onisowo Ajao Brothers lati odun keji sehin, nwon ko si san owo eja na rara.

Awon Oyinbo eleja na ni eja panla ti o dara ni awon si fi sowo si won, sugbon loya awon Onisowo Ajao ni eja ti nwon fi sowo na ko dara.

---

## Awon Aboyun Gbogun Ofe Nita Faji

EKO —O fere ju adojo enia awon aboyun lo, ti nwon to sile iwosan awon onisegun ibile ti nwon sese si ile iwosan tuntun si ita Faji leti ile sinima ni opopo Willoughby ti nwon lo gba egbogi ofe ni owuro ijeta,

Akowe Onirohin wa ni nigbati on ri opolopo awon enia ti nwon pe siwaju ile kan leti oja Faji ni o mu on ya nibe, sugbon nigbati on wole ti on bere, on ri wipe awon egbe onisegun ibile, awon Nigeria Association of Medical Herbalists ni nwon nye awon enia ti a a won ko da wo lati se itoju won lofe.

Ogunlogo awon ti nwon wa sile iwosan na lana ni won da lohun; mo gbo wipe sile meji meji owo pali nikan ni nwon gba lowo won. Ibe ni dokita Z . O . Salimon ati awon nosi won jeun osan. Alagba kan ti nwon npe ni BABA ITA FAJI, Ogbeni L . A Adeshegun pelu awon Musa Oba Anigilaje ati Afolabi Dawodu se bebe nibe pelu awon akowe won. Nwon ni awon se eleyi lati fi kan awon ara Eko wipe egbogi awon da awon loju papo ni

---

**E Ra Eleti-Ofe ni ose ti mbo.**

**Ayiluka yio so otito fun awon ara Eko.**

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street, Lagos
Phone 23370; Editor; (Olotu) Ola Onatade, 15, Kosoko Street, Lagos, P O Box 467